# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE TENI GBOGBO LAWA
No. 714 MONDAY JUNE 8, 1964 (2D)

## Obinrin Kan Ju Ọmọ Rẹ Si Ile-Iyagbẹ

ẸNUGUN:- Ha! se gbogbo enia nigbati awọn onişẹ alẹ de lati gbe panu idọti ninu ile iyagbẹ ni opopo Brodrick Coal Camp ti nwọn si ri ọmọ tuntun kan ninu panu iyagbẹ na ni Alẹ ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ kẹfa oşu yi.

Ẹniti ọran na şoju rẹ şe alaye fun oniwe Irohin wa, pe nigbati awọn onişẹ alẹ na de, ti nwọn fẹ şe Işẹ wọn nwọn ba gbe garawa ile iyagbẹ na ti nwọn si şe akiyesi pe garawa na wuwo ju eyiti nwọn ngbe lọ.

Lẹsẹkẹsẹ ti o gbe garawa na de ita lati da iyagbẹ inu rẹ sinu mọto wọn ni o ba tan ina si inu garawa na ti o si ri ọmọtuntun kan nibẹ .

Lojukanna ni awọn oşişẹ na ba pe gbogbo awọn ero ti ngbe inu ile na ti gbogbo wọn si sare jade lati wa wo ọmọ nigbati awọn enia na ko jẹwọ pe awọn ni awọn l'ọmọ na ni awọn eni ana ba lọ fi ọrọ na han awọn ọlọpa.

Nigbati awọn ọlọpa yio fi de, ọmọ na ti ku, gbogbo awọn ọmọbinrin mẹwa ti nwọn wa ninu ile na ni ọlọpa ti mu nwọn si gbe oku ọmọ na si ile iwosan şugbọn awọn obinrin na ko ti jẹwọ.

# IJỌBA FẸ ŞE IDAJỌ ẸJỌ AWOLỌWỌ NINU OŞU YI

EKO:- A ngbọ hunnu-hunnu labẹlẹ pe, Apapọ Ijọba Naijiria fẹ şe idajọ ẹjọ kotẹmilọrun ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Aşiwaju ẹgbẹ Alatako ninu Ile Igbimọ Aşofin Apapọ Ijọba ati awọn enia mẹtala miran pẹlu rẹ pe sinu ile ẹjọ giga julọ fun orilẹ ede Naijiria lẹnulọlọyi.



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

Irohin kan ti a gbọ lati ọdọ oniwe irohin wa kan fi ye wa pe lati bi ọsẹ meji şẹhin ni awọn adajọ mararun ti nwọn gbọ ẹjọ kotẹmilọrun Oloye na ti nkọ ipinnu wọn lori ẹjọ n..

Ọkan ninu awọn oşişẹ Ile ẹjọ na tun sọ fun oniwe irohin wa ni opin ọsẹ ti o kọja yi pe awọn adajọ ti fẹrẹ parişẹ wọn lori idajọ na.

Gẹgẹbi akiyesi awọn oşişẹ Ile ẹjọ na, nwọn fi ye wa pe, ninu ọsẹ ti mbọ lẹhin eleyi ni nwọn o şe idajọ Oloye na ati ti awọn enia yoku pẹlu rẹ.

Nigbati oniwe irohin wa Ejongboro bere pe ọjọ wo ni nwọn lero pe awọn adajọ yio şe idajọ ẹjọ na. Nwọn desi pada pe, awọn ko le sọ şugbọn larin ọjọ mẹdogun oşu yi titi di ọjọ kẹdọgbọn awọn adajọ yio şe ẹjọ na.

Irohin kan ti a tun ngbọ kakiri ilu ninu ọsẹ ti o kọja yi fi ye wa pe, awọn Alaşẹ ọgba ẹwọn ti sọ fun Oloye Awolọwọ pe ki o maa murasile, ki o si ma a pale awọn ẹru rẹ mọ diẹ diẹ silẹ

Oniwe irohin wa Ejongboro kọ raye lọ si ọdọ awọn alaşẹ ọgba ẹwọn na lati lọ wadi ọrọ na lọdọ wọn, ki o si tun fi oju kan oloye Awolọwọ nitori are Ẹyọ Adamuorişa ti nwọn şe ni opin ọsẹ yi şugbọn yio de ọdọ Oloye Awolọwọ ni owurọ yi, lẹhinti o ba ti kuro ni ile ẹjọ giga julọ nitoripe loni ni ẹjọ ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria pe Apapọ Ijọba lori abayọri eto ikania yio bẹrẹ.

Irohin fi ye wa pe ti awọn adajọ na ba ti pari ẹjọ eto ikania eyiti yio bẹrẹ ni owurọ yi nwọn o şe idajọ ẹjọ Oloye Awolowọ.

A gbọ wipe, larin ọsẹ ti o lo kọja lọ yi ni awọn adajọ na ti pari akọsilẹ wọn lori ọrọ na.

Awọn adajọ marun na ni, Ọlọla Adetokunbọ Ademọla, olori gbogbo awọn adajọ Agba fun Apapọ Ijọba Naijiria, Ọlọla Vahe Bairahma , Ọlọla J. I. C. Taylor, Ọlọla Lionnel Brett ati Ọlọla Louis Mbanefo, olori gbogbo awọn adajọ Ipinlẹ Ila Orun Naijiria.



Ọgbẹni Latifu Jakande



Ọgbẹni Omişade

Onirohin wa kan ran wa leti pe, ni ọjọ kẹwa oşu kẹrin ọdun yi ni Ile ẹjọ gigajulọ na bẹrẹsi gbọ ẹjọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, awọn Agbẹjọro Ijọba ati ti awọn olujẹjọ na si pari ọrọ wọn niwaju adajọ ni ọjọ Eti ti işe ọjọ kẹdogun oşu karun ọdun yi.

Ni ọjọ ti awọn agbẹjọro na pari ẹjọ wọn Ọlọla Adetokunbọ da awọn enia mẹrin silẹ ninu awọn olujẹjọ na.

Awọn enia mẹrẹrin na ni oloye S. T. Ọrẹdẹhin, ọgbẹni J. S. Ọlawọyin, ọgbẹni J, Akamọ, ati ọgbẹni J. A, Lawanson,

Ki ile ẹjọ na to mu ijoko wọn wa si opin ni ọjọ na, Ọlọla Adetokunbọ se alaye pe, on ko sọ wipe awọn iyoku jẹbi, şugbọn ọrọ wọn fẹ ijinlẹ ironu nitoripe ko si ẹjọ tabi ẹşẹ kan ti o fidimulẹ ti Ijọba fi mba awọn enia na şẹjọ

Agbọ wipe Ọlọla Mbanefo ti pada lọ şi Ipinlẹ Ila Orun lẹhinti nwọn ti pari işẹ wọn, awọn adajọ yoku na yio si gba isinmi ninu oşu ti mbọ yi.



Ọlọla Ade. Ademọla
Olori Awọn Adajọ

Nigbati Ejongboro lọ bere lọwọ ọkan ninu awọn agbẹjọro Oloye Awolọw , agbẹjọro na sọ pe, "Emi na gbọ pe, nwọn fẹ şe idajọ na ninu ọsẹ yi; şugbọn nko ti ri iwe gba lati ile ẹjọ.

Bi a ba ti tun ri idi ọrọ na si ẹ o ma gbọ ninu iwe irohin wa,

# Okpara Sọ Fun Akintọla Ki O Ta Ile Igbimọ Aṣofin Iwọ Orun Ka

IBADAN:— Olotu Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati Olori ẹgbẹ Alakukọ Dokita M. I. Okpara sọ fun Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun, Oloye S. L. Akintọla kotu ile Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati le jẹki awọn ẹgbẹ Oloye Akintọla N N D P lati le mọ gẹgẹbi awọn are Ipinlẹ na ti fẹran wọn si.

Dokita Okpara sọ eyi ni gbati o ba ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Oke Ado Ibadan ni ọjọ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi.

Dokita Okpara si tun sọ pe ti nwon ba le tu ile Igbimọ na ni yio fi Akintọla ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ han pe ẹgbẹ N C N C si wa ni Ipinlẹ na.



Oloye S. L. Akintọla
Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria

Dokita Okpara si tun sọ si i pe o fihan gbangba lati igbati on ti de si Ipinlẹ Iwọ Orun ni ọjọ Iṣegun ni on ti mọ pe ẹgbẹ Dẹmọ N N D P ko le wọle ibo kan ṣoṣo ninu idibo si Ile Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ Iwọ Orun.

Olotu Ipinlẹ Ila Orun si tun sọ ninu ọrọ rẹ pe eleyi si jẹki inu on dun pelu igbo iya 'ati lẹ jẹki ẹgbẹ on ati ẹgbẹ Afẹnifẹre wa ni ajumọṣepọ lati le jẹki ijọba rere wọ ilẹ Naijiria.

Olotu na si tun sọ pe ajumọṣepọ ẹgbẹ N C N C ati A G ni yio mu iṣọ opin fi kan posi iwa alaifẹ ilọsiwaju ile Naijiria.

Dokita Okpara si rọ gbogbo awọn ọmọ ile Naijiria lati fi tọkantọkan ni isowọn si ajumọṣepọ ẹgbẹ N C N C ati A G fun ilẹ Naijiria titan ti ti ọdun yi.

Gẹgẹbi Olotu na ṣe nde ile Oloye Awolọwọ bayi ni Iyaafin Oloye H I D Awolọwọ, Alhaji D S Adegbenro ti a jẹ adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ati awọn enia jankanjankan ninu ẹgbẹ Ọlọpẹ lo si lọ pade Dokita Okpara.

Iya afin Awolọwọ fi ọti olowo giga kan ta Dokita Okpara lọrẹ eyi ti olotu na ati Alhaji D. S. Adegbenro si mu fun ẹyẹ ajumọṣepọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹ g b ẹ Alakukọ.

## IDANILOJO

Gẹgẹbi nwọn ṣe mu ọti na ni Dokita Okpara si i sọ bayi pe, "ki ẹmi ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ o gun" Alhaji Adegbenro si dahun bayi pe Ẹmi a gun fun Awolọwọ a t i Okpara"

Gẹgẹbi nwọn se ki Olotu na ku abọ si ile Oloye Awolọwọ tan, Alhaji Adegbenro si sọ fun Dokita Okpara pe on fun ni idaniloju pe ko si ibi ti Olotu na yio de ni ipinlẹ yi ti nwọn ko ni fun ni iyẹsi ku abọ.

Alhaji Adegbenro si tun sọ ninu ọrọ rẹ pe fun irin ajo Dokita Okpara si ipinle yi, pe y i o fi han gbangba pe i l ẹ Naijiria si jẹ ti ẹgbẹ Alakukọ ati Afẹnifẹre.



Dokita M, I. Okpara
Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila—Orun Naijiria

Alhaji Adegbenro si tun sọ pe elevi jẹ aisi akoko fun awọn ti o sọ p e ki Dokita Okpara ma se wa si Ipinlẹ pe gbogbo wọn lo sa kuro ni Ipinlẹ na laiduro lati wa ri iru ẹyẹ ati iyi ti olotu na gba ninu irin ajo rẹ si ipinlẹ na

# YẸYẸNATU

## ONIYẸYẸ EKO

Yẹyẹnatu: Alọ o
Olotu:- Alọ
Yẹyẹnatu Tani mọ
Olotu:- Emi mọ
Yẹyẹnatu:- Ẹ k u n para, ẹkun para, ẹkun parapara de ile amọtẹkun. amọtẹkun salọ ninu ile Kini o?
Olotu:- Iku ni
Yẹyẹnatu:- Haha. ẹ ko mọ
Olotu:- O dara, kini ti ki i se iku?
Yẹyẹnatu:- Ẹyin na ẹ ro nkan miran
Olotu:- Ṣebi bi ẹkun ba ba amọtẹkun nile opin de si amọtẹkun niyẹn.

Yẹyẹnatu:- Yẹs, beni. Nitorina lo ṣe kuro nile
Olotu:- O ṣe wa sọ pe iku ko ni itumọ alọ na?
Yẹyẹnatu:- Iku ko se
Olotu:- O dara, kini?
Yẹyẹnatu:- A-Miky Power ni
Olotu:- E wo lo tun njẹ A-Miky Power

Yẹyẹnatu:- Okpara, ọ g a N C. N. C.
Olotu:- Hahaha, on l'ẹkun para, ẹkun para ẹkun parapara to de i l e amọtẹkun ti amọtẹkun sa ninu i l e. Hahaha Tani amọtẹkun?
Yẹyẹnatu: S L Akintọla kẹ
Olotu:- Bawo?

Yẹyẹnatu:- Ṣe ẹ mọ pe NCNC ki i ṣẹ g b ẹ NNDP, ṣe ẹ mọ pe ila pọ pupọ lara amọtẹkun ṣe ẹ mọ pe afarawe ẹkun ni amọtẹkun nṣe?
Olotu:- Lootọ ni, ṣugbọn bi Okpara ba ba S L A nile, opin ko le de si SLA kẹ
Yẹyẹnatu:- Opin a de si NNDP
Olotu:- Bawo?

Yẹyẹnatu:- Ẹnu mi kọ ni ẹo ti gbọ. Bi ẹ ba ri Fani Kayọde ti o kuro nilu, bi ẹ ba ri Benson ti ko le duro de Okpara bi ẹ ba ri baba Dele ti o kuro nile ki A-Miky to de, e bi wọn
Olotu: Ṣe iwo lo mọ, sọ ọ

Yẹyẹnatu:- O dara k i n i nwọn nsa fun Okpara fun ti i ẹru ki awo ma ya kọ ko lo ba nba wọn?
Olotu:- Nwọn ko fẹ e ri i ni nitoripe awọn ọba ko fẹ ri i

Yẹyẹnatu:- Ki iṣe n i t o r i awọn ọba ko fẹ ri i, ilu ti nwọn gbe fun awọn ọba ni nwọn nlu, orin ti nwọn kọ ni nwọn ngbe
Olotu:- O fẹ sọ fun mi pe awọn ọba ti sọ ara wọn di aja oṣelu ni I w ọ Orun

Yẹyẹnatu:- Nko jẹ sọ bẹ, ṣugbọn ibi wọn ba sọ fun wọn ni nwọn nlọ Tani ko mọ ọgbọn ka kọwe ka halẹ mọ enia
Olotu:- Pe kini
Yẹyẹnatu:- Bi o ko ba ṣe bayi, bayi ni yio ṣẹlẹ
Olotu:- Họwu nibo?
Yẹyẹnatu:- Gbogbo eyiti ẹ nṣe fun wa yi na nkọ?
Olotu:- Ohun to wa nibẹ ni pe iuiti enia ba wa ni o nṣe, ẹniti o ba si ku enia ku ni a nba jaiye.

Yẹyẹnatu:- Paapa a i y e ijẹkuje
Olotu:- Ẹni ba to aiye jẹ lo njẹ ẹ kẹ. Akoko ni
Yẹyẹnatu:- Lootọ ni ṣa, bi ko ba jẹ akoko oluwarẹ nwọn a moolu oluwarẹ ni
Olotu:- Yẹs kẹ

Yẹyẹnatu:- Ẹnyin ko ri lagbaja ti nwọn moolu ntoripe o tako tẹmẹdu
Olotu:- On na ṣe n t a k o a w ọ n afọtẹjoye ati afọtẹgbade
Yẹyẹnatu:- Ṣugbọn bi aja ba foju kan ẹkun nkọ
Olotu:- A sa lootọ, ṣugbọn ki ẹkun to de nkọ, aja ti fẹrẹ jẹ gbogbo adiẹ adugbo tan

Yẹyẹnatu:- Yẹs lootọ ni
Olotu:— Ṣugbọn awọn ala dugbo yẹn gọ ni
Yẹyẹnatu:- Rara, ti nwọn ba fẹ gba adiẹ lẹnu rẹ o ma nbu wọn jẹ
Olotu:— Ni nwọn ba nfi i sile. Bawo ni nwọn se wa fẹ bọ lọwọ rẹ?
Yẹyẹnatu:— Ni nwọn ba ranṣẹ si ẹkun
Olotu:— Ha-hẹn ko le pa aja

Yẹyẹnatu:- Ṣugbọn ki ẹkun to de aja ti salọ
Olotu:- Nwọn bọ niyẹn
Yẹyẹnatu:- Aja a tun pada bi ẹkun ba lọ
Olotu:- O maṣe o
Yẹyẹnatu:- Ọrọ na su mi your worship, o digba.

# IWE SI OLOTU

## E Tun Anikantamọ Ṣe

Olotu, Kara o le o. Inu mi yio dun pupo ti ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin alarinrin lati kesi Ijọba Ibilẹ Eko nipa adugbo wa ti o ba jẹ ti ko si ṣe rin ni asiko yi

Ẹ jowọ Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko ẹ ba wa tun adugbo Anikantamọ titi wa si Olushi ati adugbo ti nwọn npe ni "Old Arọloya ṣe awon adugbo wonyi bajẹ pupo nwon ko si ṣe rin ni asiko ti awa yi nitorina a bẹ Ijoba rere yi ki nwon o tete ba tun adugbo na ṣe, Kansilo Imoru oro na di owo yin o

A o ma reti owo yin o

Emi ni
Jimọh Lasisi

EKO

## E Kọ Ile-Iṣẹ Fun Wa

Mba dupẹ bi Olotu Irohin Imọlẹ ba le gba mi ni aye lati ba Ijọba Iwọ-Orun Naijiria ki nwọn o fun ni ni awọn nkan ti o nje wa niya ni ilu Ogbomọshọ.

A nfẹ ki Ijọba o kọ ile-iṣẹ si ilu Ogbomọshọ, nitori ko si iṣẹ ni ilu yi, ọpọlọpọ awọn ọmọ wa ti o njade ni ile-iwe kekere ti awọn obi wọn ko ni agbara ati ran nwọn lọ si ile Ẹkọ giga ni ki ri iṣẹ se ti Ijọba ba si kọ ile-iṣẹ ni orişirişi eyi yio si tundi aiko ri iṣẹ ṣe awọn ọmọ wa ku, nitorina a lero pe Ijọba rere yi yio tete ṣe eto ati kọ awọn ile-iṣẹ na.

Olotu, mo dupẹ aye ti ẹ gba mi, Iwaju ni ọpa ẹbiti yin yio ma resi o,

Emi ni,
Emmanuel Taiwo
OGBOMỌSHỌ

## E ku Iṣẹ o, Olotu

Mo ki Olotu Irohin-Imọlẹ pupọ, ẹ ku Iṣe, Oluwa ki o wa pẹlu nyin. Ojoojumọ ni a ngbadun Ọwọ nyin nipa awọn ọrọ Olotu ti ẹ ma nsọ, ti ẹ si fun awọn ara ilu ni Ọpọlọpọ imọran, paapa nipa awọn Irohin ti a ri ka ni Ojojumọ, ti a ko ba ni ṣe ere ni ẹsọ, iṣẹ nlanla ni ẹ nṣe fun wa awa na si ngbadun yin.

Oluwa yio tun bọ ma sẹ atọna nyin, ẹ ko ni lugbadi ofin Ijọba, eni elẹni ko ni gbaşe yin o.

Lakotan Ọrọ mi yi, mo bẹ yin pe ki ẹ ba wa ṣe ọna bi ao ti ṣe ma ka ọrọ yeyẹnatu ni Ojojumọ dipo Ọsẹsẹ ti a nkan.

Mo si lero pe eo ba wa se eto nipa rẹ Ao ma reti esi o.

Emi
Abiọdun Ogunlọwọ
IBADAN.

## Wundia Egioyọpo, Ọdi Ọwọ Yin

Olotu ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin Oloyin mọmọ lati ba awọn wundia ilu Egiọyọpo sọrọ atata lori iwa oju ko gbe ibikan ti nwọn nhu ni asiko ti a wa yi iwa na ko dara to bẹni ko si ba igbomi,

O di ti iwa awọn Ọmọbinrin na lati mọ fẹ awọn Ọmọ ilu wọn mọ a fi awọn alejo ati ara ilu miran

Awọn asiwaju nyin ko hu iru iwa ti ẹ nhu yi rara, nitoripe ẹsin ti iwaju ni ti ẹhin lati wa sare Ẹhin ko ṣe bẹ rara wa ti o mu nyin ni ẹ nhu si ara nyin.

Ki ẹ si tun sọra fun iwa ojukokoro ti o nba alafia ati anfani nyin jẹ ti o si nfa oyun elẹsiorin ti ẹ si nba Ọmọ ti ko ni baba jọ.

Mo dude lọwọ Olotu fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
Amọdu
IGBAJA.

## EYi KO ye mi

Olotu, Inu mi yio dun pupọ bi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi laye diẹ ninu iwe rẹ ti nta bi akara gbigbon lati bere ọrọ ti ko ye mi yi lọdọ awọn ọlọgbọn ati Oloye ti nka iwe yio lojojumọ ibere na jẹ nkan ti o sa sumi loju inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le la ọrọ na ye mi.

Nigbati mo fẹ ṣe igbeyawo alọ si ile ejọ lati lọ igbeyawo (Court Marriage )a si fi ọwọ bọ iwe iwe pe, ao ni ko arawa silẹ titi ti iku yio fi ya wa.

A si nba igbeyawo na lọ ko pẹ ko jin na edeaiyede bẹ sile larin wa, mo si emu suru fun obinrin na, şe ẹm ọ w iwa obinrin miran

Ọrọ re o repetẹ! olotu, oju rẹ ko ni ribi o, bẹni Olodumare ko ni jẹki poro o yọrọ rẹ ko doya, gbogbo ẹyin onkawe mi, mo nreti imọran nyin nipa ọrọ t i o di e e w e sinu mi yi lati ọwọ ẹnyin ojogbọn.

Emi ni
Ọmọ Afọgbọn Sapara
AJASSẸ — IPO.

## EGBOGI JEDIJE

BERE EGBOGI



### "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Okunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn maa poowo wọn fun iwosan rẹ şugbọn boya la leri mẹwa ninu awọn ogun o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Şubbọn awa ko ro be rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun obẹrẹ akana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko mẹ ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Şuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni, tabi ti arin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egboogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani şẹşẹ wa idi rẹ kio si panwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijedi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata gboro Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji

## Ibanujẹ Tabi Irora Rẹ de Opin

### Ayọ De

Bere Ojulowo Egbogi awọn Faranse gidi ti a npe ni

### 'CORSIVER'S



Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a şe ni pataki Fun „ARỌN KINIŞA" tabi LATANATAN" ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹraku tabi lati ma şe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko. Lẹhin ti o ba i lo egbogi arọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ẹhin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ibadi gige tabi sisan ba nyọ ọ lẹnu sibẹsibẹ bere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo şe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn amodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi na nje ni şọbu awọn.

Waterloo Stores
8, Palm Church Street; Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Oja Ita Faji Lagos.)
ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos
NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.]
ATI NI AWỌN ŞỌBU IBADAN:—
IŞẸ LODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

# Ko Si Ofin Isede Ipade Ni Ipine Iwọ Orun

EKO Laipẹ yi Irohin de ọwọ wa lati ọdọ awọn ọlọpa l'Eko pe ko si ofin isede ipade gbangba ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria. Gẹgẹbi irohin to de ọwọ wa ni ọjọ Ọjọ'Ru ti işe ọjọ kẹta oşu yi fi ye wa pe lati ọdọ ọga Ọlọpa agba lati Eko ni irohin na ti wa.

Irohin na fi ye wa pe ofin iwọde gbangba si wa ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria gẹgẹbi irohin kan to wa ni nu iwe irohin Daily Times ti o sọ pe awọn ọpọlọpọ mọto ti fẹ na to le olotu ipinlẹ ila orun Naijiria, Dokita Okpara pe awọn ọlọpa kọ lati jẹ ki awọn mọto na to tẹle e lasiko irin ajo rẹ si Ibadan,

Ni edakeji ẹwẹ, irohin na si fi ye wa pe Ọpọlọpọ awọn moto lo to telẹ Dokita Okpara, şugbọn awọn Ọlọpa si da nwọn duro fun eto ofin iwọde gbagba to wa lode lati ma lọ diẹdiẹ ati awọn moto miran ti ko tẹle Olotu ipinlẹ ila orun.

Irohin na tun ti ye wa pe ko si wọde gbangba ni Ibadan ni ọjọ ti Olotu ipinlẹ ila Orun de ilu Ibadan gẹgẹbi iwe irohin kan şe sọ sugbọn ki işe Irohin-Imọlẹ.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AGUARIUS Jan 20-Feb 18 Gbogboo nkan to jẹ ti ara rẹ lo wu ọ julọ, gbọgbo ero ọkan rẹ jẹ ala ti ko ni şe. Bi o badi ọsan ija kan yio şẹlẹ larin iwọ ati oluwarẹ,

PISCES (Feb 19- Mar 20) Ki olo gbogbo ọgbọn ori rẹ si ọran ara rẹ iwọ yio ba obinrin kan se ipade ti ẹ o ma ba ara nyin ta ọrọ awọn ẹbi rẹ kan yio ru ọ loju, şugbọn dupẹ lọwọ ori rẹ.

ARIES (Mar 21-April 19) Inu rẹ yio ma dun ọkan rẹ yio si kun fun ayọ lati le sọrọ pataki kan ti o diju Maşe jiyan lori ọrọ ti ko to nkan.

TAURUS (April 20-May 20) Ọjọ oni dara fun ọrọ ara rẹ şugbọn o yẹ ki a şọra gẹgẹbi oti mba awọn enia nlanla pade. Irohin aladun ni iwọ yio ma gbọ loni.

GERMINI (May 21 June 21) Ọjọ oni dun o si dara fun nipa owo ati asiki iwọ yio lọ sibi ase kan nibẹ ni iwọ yio ma ba Obinrin kan ra, titi nkan yio ti kọja sinu nkan, maşe jẹki ọrẹ rẹ jowu

CANCER (June 22 July 25) Ọjọ oni le, nşe ni ki o şe snrọ, ki o maşe ja, bi ija ba lọ bẹ silẹ, n k a n yio bajẹ.

LEO JUly 23 Aug 22 işẹ yio d i ọ lọwọ p u p ọ loni, o nfẹ oniranlọwọ iwọ yio jere ninu işẹ rẹ n a w a wa Oluranlọwọ.

VIRGO Aug 23 Sept 22 Iwọ yio gbọ irohin ayọkan oni nipa ere ti o jẹ lori Ariwo diẹ yio wa bi o ti wu kio ri maşe ba awọn ẹbi rẹ sọ ọrọ aşiri kọkan.

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Iwọ yio rin irin ajo lọ si ọna jijin lati wo ojulumọ rẹ kan. Şugbọn iwọ pẹlu obinrin kan yio şe gbonmi si omi koto yio ma jowu si ọ, iwọ yio yayi larin ẹgbẹ ati ọgba,

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Ire ni ni gbogbo ọjọ oni yio jẹ fun ọ, Iwọ yio ri iwe gb.. loni o si jẹ lati ọdọ ọbinrin igbadun si mbẹ larin iwọ ati awọn ẹbi rẹ,

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Gbogbo enia lo nfẹran rẹ, iwọ yio si ri iranlọwọ pupọ lati ọdọ wọn, Iwọ o ri ere nla je, ohun kan ti o si ti nfẹ yio tẹ ọ lọwọ Rin faaji lọ si oJe loni,

CAPRICON (Dec 22-Jan 19) Irọrun ni ọjọ oni yio jẹ fun ọ. ọpọ nkan ti iwọ nfẹ ni iwọ yio şe ipinu rẹ, Iwọ yio jẹgbadun pẹlu olufẹ rẹ kan, agbalagba ẹbi rẹ kan nfẹ iraulọwọ rẹ


## CLASSIFIED PAGE

"KIU FUNG MANUFACTORY BOX 3812, HONGKONG, IMITATION JEWELLERY WIRE HOOKS"

## MODUPE PRINTNG PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* MODUPE PRESS *Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*

Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbose Street,**
Phone 21985, Lagos.

## SEDO— PAYAL

Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi fun 'Ipara" ti awọn ..ilera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu lode ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun nigbakugba, A'efọ, Egbo ẹsẹ orişirişi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ bi adain egbo ekusẹ tabi ekuse tabi lapalapa, Ela tabi ara su,Akọ, inarun ati orişirişi orun "Arε" miran gbogbo





Gbiyanju lati dan egbogi tiiun awọn ara Ilu Tatanb ruaşe ti nwọn npe ni "PAYAL" wb larin ọjọ mẹta run a yio ma rohin rẹ fun awọn ẹlomiran pẹlu Egbogi b a yi ki şe awọn rọl irobi ti wọn nta kakiri ilu ni owo pọku. Ojulowy egbogi orun arun ara haunhaun ti ko si şişẹ ye meji ninu eleyi si yatọ patapata si awọn ẹgẹrẹmiti adimọwọ ti won nta kaklri igboro ati ni agbereko gqogbo pẹlu Orisi meji re lo wa Kekere ati Nla.

Bere egbegi Ajẹbidan SEDO PAYAL yi ni şọbu awọn PILENAB MIXTURE,

Egboigi olomi dara julọ fun awọn ọmọde ti jẹdijẹdi bi ako gbonse dede ba nyọ lenu bere rọ ni

WATERLOO MEDICINE STREES
FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

# Eyi ni awọn ọjọ Oja Ilẹ Yoruba

## ỌJỌ AJE JUNE 8 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ. | Mushin Badagrey |
| ABEOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkọ Omida Itwọ |
| IBADAN | Itoko, Ṣojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJEBU | Ikẹnnẹ, Okun-Ọwa Eruwo Omu Mamu |
| IJESHA | Oshu, Itagun, Odogbo Idokọ Iloko |
| EGBADO | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke–Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ IṢẸGUN JUNE 9 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ. | Ikẹja, Agege |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla |
| IBADAN | Ajegunlẹ, Idọgọ, Olodo. Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imope |
| JẸSHA | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilo-Idiẹmi |
| EKITI | Okemẹsi, Ifaki. |

## ỌJỌ'RU JUNE 10 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo Ejinrin |
| ABẸOKUTA | Ijoko Ibẹrẹkodo, Asu, Wasinmi Owode |
| IBADAN | Akẹroro, Idọfin, Lagun, Sagb Ogunṣana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Sagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi Ile |
| ẸGBADO | wlagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Su-Aa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ JUNE 11 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun–Eko, Ojuwoye, |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN | Fẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Baba lokuta' Ijaiye-Orile |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe ṣara, Imodi, Ishan, Akẹsan, |
| JẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọo Ilaṣẹ, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado-Odo |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun |

## ỌJỌ ẸTI JUNE 12 FRIDAY

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida Ilawọ |
| IBADAN | Itoko, Sojukonkọ, Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun—Ọwa, Ẹruwọn, Omu. Mamu |
| IJẸSHA | Osnu, Itagun, Odogbo, Idoko Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ ABAMẸTA JUNE 13 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWON ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Berẹkodo, Aṣu, Wasinmi Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun Ṣagbẹ, Ogunjau, Mọlete, |
| IJẸBU | Aiyepe, Shagamu, Itaoṣu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ, Oyingbo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Oja–Ọdua, Sunwa Iboro, |
| EKITI | Ilogbo Ishan. |

## ỌJỌ AIKU JUNE 14 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGEZGBE RẸ | Ikẹja,Agege, Ebute-Ero Ọjọ Ajido |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunle, Idọgọ Olodo |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imodi |
| IJẸSHA | Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Iwara, Ejiro, Odo, Ibokun, Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi Ifaki |

## ỌJỌ AJE JUNE 15 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye Ikosi, Ẹpẹ Atan Agbado, Ifọ Itori, Itoku |
| ABẸOKUTA | Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ogburo, Ẹgbẹ |
| IJẸBU | Babalokuta. Ijaiye Orile. Ilishan, Isara, Imodi. |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọ. |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado-Oda. |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun. |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati ọwọ EJON'GBORO

### EKO

Gbogbo enia lo pe si eti odo ọsa ni opopo Adeniji Adele nigbati igbi omi gbe oku ọkunrin kan wasi Ebu te awọn ọlọpa ti gbe oku na lọ si ile iwosan lakulaku

### EBUTE MẸTTA

Ariwo ta nigbati awọn mọto meji kan Nos EO 35 90 ati 00 7864 fọrisọ ara wọn ni Opopo Apapa Ro ad awamọto kan si fara gbọgbẹ, lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpa gbe lọ si ile iwosan fun itọju.

### IKOYI

Idamu nla ba gbogbo enia nigbati ọkunrin kan Edward Idịe ti nse isẹ olu-kọ ile iwe St. Saviors subu lulẹ ti osi ku loju ọnabi wọn ti gbe lọ si ile iwosan.

### APAPA

Ariwo ekun ta gee nigbati ọmọkunrin kan Chkwemeka Okolo eni ọdun merindilogu ku lojiji ni bareke ọlọpa lẹsẹ ni awọn ọlọpa gbe lọ si ile iwosan labẹlabẹ fun iyẹwo

### APAPA

Jinnijinni dabo gbogbo enia nigbati ọṣa ọlọpa okọ oju omi gẹẹsi jabọ sinu odo ọsa ọlọpa ti oku rẹ lọ ṣi ile iwosan lakulaku,

### EKO

Idamu nla ba gbọgbo awọn o ngbe inu ile nọmba 16 Ọdu fa street nigbati ọkun rin kan ti o gbe 54 Cleak street Surulere wa wo ọrẹ rẹ ti osi wukọ ku sinu ile na Lẹsẹkẹsẹ ni awọn ọlọpa de ti nwọn si ri ẹjẹ ti o njade lẹnu nwọn ba gbe oku rẹ lọ si Ilewosan lakulaku fun iyẹ wo Dokita,

### IWAYA

Ogbẹni Salami ti o ngbe 42, Owode Street, lo mu ọdaran kan fun awọn ọlọpa nitoripe o fọ ilẹkun ile rẹ o ṣi ji pọnun (£4) gbe ninu ile na,

### EKO

Ariwo ta gee e. nigbati mọto kan EA 4343 kọlu ọmọkunrin kan ni opopo Ojoriwa Eko, ṣugbọn ọmọ na ku bi nwọn ti gbe de ile–iwosan,

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 714 MONDAY, JUNE 8, 1964 (2D)


## Baba Kan Şeesi Yin Ọmọ Rẹ Ni'bon!

Jos:- gbogbo enia bẹrẹsi sare jade ninu ile lati wo baba kan nigbati o gbe ọmọ rẹ jade si inu ilu ni kọkọlọrun ti o si gbe oku ọmọ rẹ lọ si Teşan awọn Ọlọpa ni ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ kẹfa oşu yi

Pẹlu omi oju ni baba na fi nrojọ ni Teşan awọn Ọlọpa pe on ati ọmọ on ni awọn jijọ lọ si igbo-ọdẹ ti awọn lọ pa ẹran igbẹ. Nigbati onyinbọn siẹiyẹ kan ti ẹiyẹ na si bọ silẹ, ni on ba ni ki ọmọ on o lo mu ẹiye na wa

Nigbati ọmọ na de idi igi na ti ko ri ẹiyẹ ni o ba wo oke ori igi na, ni o ba gun igi lọ lati lọ mu ẹiyẹ na, nigbati o de oriigi ọwọ rẹ ko to ibiti ẹiyẹ na ha si ni o ba mi igi pe ki ẹiyẹ na le bọ silẹ.

Şubọn nigbati baba na ri igi ti o nmi ni o ba yinbọn si i ti ko si mọ pe ọmọ on ni on yinbọn si a fi igbati ọmọ ja silẹ lori igi ti baba na sare debẹ ti o si ri ọmọ rẹ ti o nja rapa nilẹ bi ejo ti a şẹşẹ ge lori.

Lẹsẹkẹsẹ ni baba na ba fi ibọn ati ẹran ti o pa sile ti o si gbe ọmọ rẹ lọ si Teşan awọn Ọlọpa.

Awọn olọpa ti gbe oku ọmọ na lọ si Ile iwosan Lakuşaku, nwọn si nwadi ọran na lọwọ.

## Igbimọ Ẹgbẹ Awọn Oşişẹ Sọ Pe:

# Ko Si Ẹniti O Gbimọ Lati Doju Apapọ Ijọba Bolẹ

EKO:- Alhaji Haruna Popoọla Adebọla, Asiwaju Igbimọ ẹgbẹ awọn oşişẹ sọ ni Eko ninu ipade kan ti o ba awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ti nwọn da işẹ silẹ şe alaye pe, ko si ẹniti o gbimọ tabi ti o fẹ doju Apapọ Ijọba bolẹ gẹgẹbi awọn kan ti nsọ kakiri igboro ilu.

Alhaji I., P. Adebọla tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe, Apapọ Ijọba Naijiria ti nwa ọna lati ri i wipe gbogbo awọn Oşişẹ pada lọ si ẹnu işẹ wọn kia-kia.

Ni owurọ yi, awọn ọga Agba Ile işẹ Minista Alamojuto eto işẹ ati alafia fun Apapọ Ijọba Naijiria ti şe eto lati pade awọn Asiwaju ẹgbẹ awọn Oşişẹ jake jado orilẹ-ede yi

Ni ijẹta ọjọ Abamẹta ti işe Ọjọ kẹfa oşu yi ni awọn Alaşẹ Ijọba na ti fẹ ba awọn oşişẹ sọrọ, şugbọn Alhaji Adebọla şe alaye pe o yẹ ki awọn olori ẹgbẹ awọn oşişẹ ni Ipinlẹ mẹrẹrin Naijiria o le wa ninu iru ipade bayi, nitorina, nwọn ko şe ipade na mọ ni ijẹta, nwọn wa yẹ ẹ si owurọ yi.

Irohin fi ye wa pe, lati owurọ ana ni awọn Asiwaju ẹgbẹ awọn oşişẹ lati Ipinlẹ ti de si Eko fun Ipade ti nwọn yio şe ni Eko lowurọ yi.

Şugbọn, biotilẹribẹ na, awọn Asiwaju ẹgbẹ oşişẹ ti kesi gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ wọn pe, ẹnikẹni ko gbọdọ pada si ẹnu işẹ, ki gbogbo wọn o ma a lọ si ibi işẹ wọn.

Şugbọn nwọn ko gbọdọ fi ọwọ kan ohunkohun şe ki nwọn si man joko tẹtẹrẹ laifọwọkan ohunkohun şe, nile işẹ wọn titi aşẹ yio fi yi ipinnu wọn pada.

Ninu ọrọ rẹ fun awọn oşişẹ Alhaji Adebọla sọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ pe, 'Irohin agbọsọ kan ti awọn enia nsọ pe, awọn oşişẹ fẹ doju Ijọba bolẹ ni nwọn şe da işẹ silẹ' Alhaji Adebola ni irohin na jẹ "işilọna ti ko si jẹ otitọ"

Alhaji Adebọla ni ọrọ na jẹ eyiti o ya enia lẹnu lati gbọ, şugbọn on fẹ fi oke le e fun gbogbo enia gbọ pe, "isọkusọ ọrọ" ni awọn enia ti nsọ ọrọ na nsọ kakiri, ọrọ na si jinna si ete ati ero ọkan awọn oşişẹ

Boya ti nwọn ba pari ipade ti nwọn fẹ şe loni, nwọn le pada si ẹnu işẹ wọn.


TRADITION REFLECTED IN PROGRESS



DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.



Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone:- 21985
Editor:- TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos (8/6/64)